**ILÉ-IṢẸ́:**

**OLÙWÁDÌÍ ÀGBÀ:**

**NỌ́ŃBÀ IṢẸ̀:**

**ÀKOLE IṢẸ́-ÌWÁDÌÍ:**

A fẹ́ kí o kópa nínú iṣẹ́-ìwádìí. Kí o tó gbà láti kópa, ó di dandan kí o kọ́kọ́ mọ̀ ní ṣokí nípa ìwádìí yìí, mímọ̀ ní ṣókí yìí ni yòó fún ẹ ní àǹfàní láti mọ àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí yòó ràn ẹ lọ́wọ́ láti pinnu bóyá ó fẹ́ kópa tàbí o kò fẹ́ kópa nínú ìwáàdí yìí.

Kíkópa rẹ nínú iṣẹ́-ìwádìí yìí kì í ṣe tipatipá, o kìí yóò sì pàdánù àǹfàní kankan tí o kò bá kópa, tàbí tí o bá pinnu láti má tẹ̀síwájú bí akópa.

Lẹ́yìn tí o bá ti mọ̀ ní ṣókí oun tí ìwádìí yìí dá lé, àwọn agbátẹ̀rù nípa iṣẹ́-ìwádìí yìí yóò jẹ́ kí o mọ̀ ní kíkún sí i àwọn nǹkan wọ̀nyí:'

1) àwọn kókó, ìgbésẹ̀, àti àkókò tí iṣẹ́ ìwádìí yóò gbà
2) àwọn ìgbésẹ̀ ìwádìí tó jẹ̀ mọ́ dárawò
3) àwọn ewu tàbí àǹfàní ó jẹ mọ́ ìwádìí
4) ọ̀nà àbáyọ mìíràn tó jẹ mọ́ ìtọ́jú tí yóò ṣe àǹfàní
5) Bí a ó ṣe rí i dájú pé a kò da ìgbẹ́kẹ̀lé tí a ní nínú ara wa

Àwọn agbátẹ̀rù nípa iṣẹ́-ìwádìí yìí yóò jẹ́ kí o mọ̀:

1) Àwọn ẹ̀tọ́ ìlera tí ó tọ́ sí ọ nígbàkúúgbà tí o bá fara pa tàbí ní ìjàǹbá;
2) àwọn ewu tí a kò fójú sí ṣùgbọ́n tí ó lè ṣẹlẹ̀
3) ìṣẹ̀lẹ̀ tó lè mú kí àwọn olùwádìí dẹ́kun kíkópa rẹ
4) Kíni iye owó tó tún lè ná ọ sí i;
5) Kí ni yóó ṣẹlẹ̀ tí o bá dẹ́kun àti máa kópa
6) Nígbàtí o bá gbọ́ àbájáde ìwádìí wa tuntun eléyìí tó lè mú kí o má fẹ̀ẹ́ kópa mọ́
7) Àwọn ènìyàn mélòó ní yòó jẹ́ akópa;
8) Lílo àwọn ohun tó jẹ mọ́ ara rẹ láti fi ṣòwò
9) Ǹjẹ́ wà á tilẹ̀ mọ èsì àbájáde èsì ìwádìí yìí
10) Ǹjẹ́ ìwáàdí yìí yòó tilẹ̀ fi gbogbo ìpele ìṣẹ̀dá-èèyàn ní ìlànà sáyẹ̀nsì hàn; àti
11) Ṣé ó ṣe é ṣe kí a lo àwọn nǹkan tí ẹ sọ fún wa nínú iṣẹ́ ìwádìí mìíraǹ ní ọjọ́ iwájú.
12) Fún ìdániwò: A ó rí gbogbo àlàyé ní https://www.clinicaltrials.gov, gẹ́gẹ́ bí òfin Amerika ṣe là á kalẹ̀. Àbájáde ìwádìí ní ṣókí yóò wà ní orí àyélujára. Ẹ lè wá a nígbàkúgbà.

    Síwájú sí, ẹ lè rí àlàyé ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà NIH ní https://www.clinicaltrials.gov

Tí o bá fẹ́ kópa, rí i dájú pé ó gba ẹ̀dà ìwé yìí tí a fọwọ́ sí, àti ìwé ní ṣókí lórí ìwádìí yìí

O lè bá mi sọ̀rọ̀ *(Orúkọ)*_____ *(fóònù)* _____ nígbàkúgbà tí o bá ní ìbéèrè nípa ìwádìí yìí.

O lè bá mi sọ̀rọ̀ *(Orúkọ)*______ *(fóònù)* _____ nígbàkúgbà tí o bá ní ìbéèrè nípa ẹ̀tọ́ rẹ gẹ́gẹ́ bí akópa tàbí ẹni tí ó ní ìjàǹbá.

Fífi ọwọ́ sí ìwé yìí tí fihàn pé o ti gbọ́ àlàyé kíkún gẹ́gẹ́ bí akópa, o sì ti gbà láti kópa làí jẹ́ pé wọ́n fi tipátipá mú ọ.

______________________________ ______________________________ ______________________________
Àkópa fi ọwọ́ sí ìwé | Orúkọ Akópa | Déètì

______________________________ ______________________________ ______________________________
Ẹlẹ́rìí fi ọwọ́ sí ìwé* | Orúkọ Ẹlẹ́rìí | Déètì

***ABALA TÍ OLÙDARÍ NÍ NIH GBỌ́DỌ̀ FI ỌWỌ́ SÍ NÍPA LÍLO ÒGBUFỌ̀:**

____Ògbufọ̀ tó gbọ́ èdè Òyìnbó àti èdè akópa ni ó ṣe <u>ẹlẹ́rìí àti kòkáárí</u>. Olùwádìí kò tún gbọdọ̀ jẹ́ ẹlẹ́rìí.

____Ògbufọ̀ tó gbọ́ èdè Òyìnbó àti èdè akópa ni ó ṣe <u>kòkáárí ṣùgbọ́n kò ṣe ẹlẹ́rìí</u>. Orúkọ tàbí nọ́ńbà ìdánimọ̀ ògbufọ̀ ni:_____________________________________.